**Akiyesi**

A nfẹ Ẹniti yio maba wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilọrin tabi Ilu miran. Ẹ kowe si ọdọ Ọgbẹni: R. O. Adedeji Esq. Ni P. O. Box 12. Ilọrin

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Notice**

Ema polowo oja yin sinu Iwe Irohin Imole.

VOL. III No. 150 MONDAY MAY 30 — JUNE 5 1960 KỌBO KAN (1d)

# Gongo so ni ibi iwadi Ogbeni Elias

A gbo wipe oro ko dun nibi iwadi ti Ogbeni Elias nse larapa ede koyede ti o sele larin awon Osise ogba Reluwe ati awon Olotu won. Nigbati awon Agbejoro fun totun tosi fi mba ara nwon jagun ofin.

Ọgbẹni Adewale Thompson yọ Iwe ofin kan jade o si fi le Ọgbẹni N. A. Kuforiji lọwọ wipe gẹgẹbi ọrọ ti Ọgbẹni Kuforiji sọ wipe awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ ko ni ẹtọ lati da Ẹgbẹ alapapo silẹ, ki o tọka ibikan fun Oluwadi ọrọ ki nwọn ri.

Ibẹ ni Oloye H. O. Davies ti dide, o si tako nkan ti Adewale fẹ ṣe na wipe, niwọn igbati Ọgbẹni Kuforiji ko nṣe Lọya ko ni ẹtọ lati si Iwe Ofin.

Oluwadi ọrọ na dahun pe " ohun ti o jẹki Ọgbẹni Adewale ṣe bẹ ni wipe Ọgbẹni Kuforiji ti sọ asọrege ọrọ Lọya Adewale bere lọdọ Kuforiji ki o se apejuwe ofin ti o gbojule, ki o to sọrọ ti o sọ yẹn.

Ọgbẹni Kuforiji dahun wipe ni ọdun 1949 ti Ọgbẹni Brooke wa ṣe itọsọ ọrọ nihin, ọrọ ti oluwadi sọ lọjọ na ni mo sọrọ le lori, Oloye Davies sọ wipe bi akojọ ẹgbẹ na ko ba bọ si ẹtọ, iyẹn ko wipe o ti lodi si ofin.

Adewale bere wipe ṣe o mọ pe Ẹgbẹ Trade Union Ijọba ko fọwọ si, njẹ iwọ le sọ wipe Ẹgbẹ na ko to? Ọgbẹni Kuforiji si dahun pe, rara, nko jẹ wi bẹ.

Lọya Adewale tun bere, pe ṣe iwọ mọ okunrin akọwe agba kan ti nwọn npe ni Kadiku, ti ko ni ilọsiwaju ninu iṣe re fun ọgbọn ọdun sẹhin. Kuforiji dahun pe, on ko le sọ. Nihin ni Adewale gbe yọ iwe ti akọwe kan kọ si olotu Reluwe ti o mbere lọwọ Kuforiji wipe, ṣe o mọ pe okunrin na ti le ni ọgbọn ọdun ti o ti nṣiṣẹ. Kuforiji dahun pe gbogbo awọn enia ti o nwi nwọnyi, bi o bajẹ wipe nwọn da musẹmuṣe daradara lori iṣẹ wọn, o daju wipe nwọn iba ti ni ilọsiwaju.

Adewale sọ wipe ṣe iyẹn ni wipe awọn enia na ko gbamuṣe to? o dahun pe ko nṣe pipẹ ninu iṣe ni enia fi nni ilọsiwaju, bikoṣe mimọ iṣe na daradara.

## Ijoye Ibadan sun siwaju ninu Oye

IBADAN:- Ṣeranwo gbo boroki nita Alafara nibi ile Olubadan ilu Ibadan, nigbati nwọn nṣe ti awnyewuye ti awọn ijoye ilu Ibadan ti ṣiwaju, olukuluku awọn ti o jẹ oye nwọnyi ninu aṣọ Gbariyẹ ẹtu ati Dandogo alari, a fi ẹniti o ba de ibẹ nikan lo le rohin.

Awọn isọwọ ti Olubadan ati ọwọ ti Balogun ni pataki ẹniti o jẹ oye na. Awọn ti nwọn yan ti o jẹ oye na, nwọn jawe ekika le wọn lori, awọn ọdẹ ti o wa nibẹ si rọ ibọn wọn danu.

Obinrin meji wa ninu awọn ti nwọn jẹ oye titun na, awọn Iya Afin Abiọla Agbekẹ, on lo jẹ Oye Mayẹ Iyalode ẹni keji ni Iyafin Egbinola Alakẹ Ṣokunbi on lo jẹ oye ẹkarun Iyalode.

Babesalẹ awọn Ẹgbẹ Olupapọ ti o joye Mogaji ri, ti wa di Bada nisisiyi Ọgbẹni E. A. Adeyemọ joye Arẹ Onibọn Ọgbẹni Akinbiyi di Are-ago, D. O. Okunọla di Gbonka. Gbadamọsi Abasi di Arẹgbẹ-ọmọ. Ọgbẹni Latinwa di Lẹgunna. Adeko Foko di Arẹgbẹ-ọmọ. Ọsunware joye Ajia, ati awọn ọpọ Enia bawọnni.

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Erọ Alata to dara ju gbogbo eyi ti awọn ti nlo tẹle ri lọ, lẹhin ata lilọ, o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba, ati Ẹwa ere orisirisi. £45 NI A NTA Pẹlu Ẹnjinni Petrol tabi ati pẹlu Eletriki Mutọ.

O WA NI ṢỌBU

**Akoshile Brothers**

5. Balogun Street West, P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos.

## Inland Waterways Notice No. 5/1960

It is notified for general information that the Lagos/Apapa Ferry Service will operate a normal Sunday Service during the Public Holidaps of ID-EL-KABIR, the 6th and 7th of June, 1960.

(Sgd.) G. N. WOOD
Acting Director
Inland Waterways Department

# MA FI OWURO S'ERE APA 14

Lati Owo:- J. O SHOYINKA (Mushin)

AWON ALUJANNU BERESI GBE IJA BABALAWO WON

NIGBATI AWON Alujannu ri pe owo ndun Babalawo nwon lara, ara nta nwon p a r a, nitoripe bi Akookuta ti nfi egandi la Babalawo nwon mole, bena si ni o ngba l'eti agbayira, awon Alujannu gbe ikuta, nwonfi oro nwon se opprofi nyagi, nse ni nwon difo mo Ako-okuta f'ori t'orun, jigi ti o gboora nse ni gbogbo nwon fule nwon yi lo gbiri-gbi, Ako-okuta ko s'eni s'eji, o towo bo Ako re, o fa Ida yo o si be Babalawo nwon lori.

AWON ALUJANNU YOKU FARAPAMO

Nigbati awon Alujannu yoku ti o fi fara pamo ri ohun ti o sele, won rora po apejo si koro kan eniti o ku ni Olori nwon ni se enyin papa ri ohun ti o sele s Babalawo wa tabi e ko ri.? Awon Elegbe wa papa lo ro kale bi elo yi, bi nwon yio ku ni tabi nwon yio ye ni, n ko le so, sugbon ohun kan ni mo fe so fun nyin " oju ti o pa Ojugba eni npowe" mo si fe ki e mo daju pe akotagiri Okunrin ni elevi, bi o si se si wa ogbon kan ti a le fi pa Okunrin na ni mo fe so yi ti ko ba si dara ki e tete so fun mi ki a le wa ogbon miiran kan

Ti o ba di agogo meji oru, e jeki a vo kele-kele lo si odo won, ki a si da MAJELE si o d o na, mo mo daju pe ko ni sai mu ninu omi odo na ti o ba mu u, yio ku. Ti o ba si fi bo oju lasan, raurau ni o j u re yio fo ku si ni si Onisegun ti yio le woo san lailai.

Inu gbogbo nwon dun, nwon ni Olori o wi i're, O-wi i're. Ni oruganjo ni nwon ti lo da Majele na sinu odo, olukuluku wa lo fi ara soko leti bebe odo lati fi wo bi Ako-okuta yio ti se fowo ko iau ku.

Ile mo, Ako okuta ji, o na pon-pon, egungun ara re ro koko-ko, jagun gbe ewu ati sokoto re wo O dori ko ona odo.

AKO-OKUTA DE ODO OSUMARE TA.

Bi Ako-okuta ti ni ki on tese bo odo ni Osumare ta gbogbo odo si be riri-ri bi awo Jiji, Akookuta si sunra ki, o ti mo pe nkan ipalara wa ninu odo na. On papa wa ti Egede bo enu, o te Eji-Ogbe si eti bebe odo na, o si gbe Opele re nale. Ohun ti o yo lori Ifa na ni pe:- "A ba je wi fun o, o ba je gba On lo d'ifa fun Bara-Agbonmire un lojo kini nigbati o nle pa Ale r'ile Oyo lo re ba sun, nigbati o d'orita m e t a ona pin, o w'oju ona ti nibiti o gbe ti npoyi rain-rain, ni eiye Elulu kan fo hagebage de, o duro le ni ejika o nso bayi pe, ku-u-ku-u ewu nbe nidi m o j o, o ma nbe nidi mojo, dakun-dakun te-te-te pada.

B a r a Agbonmiregun gbo, o gba o si pada. Iku Magun si fo da Ti o ba mu ninu omi yi. orun ko ni wo ba o, bi o si fi b'oju, oni yi gan ni iwo yio ri itasan mo. O pa Ejiogbe ti o te re, o bu iyanrin re o si fon sinu Odo na, nse ni odo na dudu kelekele bi aro. O miri titi o ni a se ewu nbe loko longe nigbayi ni on papa to mo pe awon Ota on ku sugbon nwon tun ku.

Akiyesi:- Lose to mbo, l'agbara Odu e o ma ka apa Kedogun (15). Gere bi Ako-okuta se fon yepe si gbe ti Eweko gbina, awon Alujannu si sa jade.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16 Bamgbose street, Lagos Phone: 21985. Olotu: E. A. Adeniji 51 Tejuosho Street Suru-Lere YABA
FUN OWO IROHIN IMOLE ODUN KAN
EKO Sile Merin ati Kobo Merin (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati OKE-OKUN Sile Mefa ati Kobo Mefa (6s/6d)

العلم يعلى ولا يعلو عليه

## E tunbo fi kun igbagbo yin

Lati Owo:— MAULVI N. SAIF. Lagos.

Lose ti o koja, mo soro die fun nyin nipa Islam, sugbon mo fe so fun nyin ni pa igbagbo ni ose y .

A gbo wipe enikan wa si odo Anobi Muhamad, ki ike Olorun ma ba, o wa bere ni pa esin Islam. Anobi se apejuwe nkan marun fun, akoko ninu re ni igbagbo.

O so fun pe akoko ninu ohun ti Musu ni lati se ni pe ki o gbagbo pe ko si elomiran a ya fi Olorun ati pe Mohamad ni ojise re. Nkan meji nwo yi ni ipilese igbagbo, beni a ko ni lati gbagbo pe Muhamad nikan ni ojise re. Igbagbo wa ni pe Mohamad je okan ninu awon ojise re, ti Olorun ti nran si araiye lori sirisi igba. Kuran so wipe ko si orile ede kan ti Olorun ko ranse si ri.



Igbagbo lo nto wa lehin ni nu iwa wa gbo gbo. Bi igbagbo na ba ti po to, be ni oluwa re yio ma ri atilehin sipa ise rere. Enia le bere pe bawo ni enia se le fi igbagbo kun igbagbo, gegebi mo ti so ni akoko wipe, igbagbo a ma se alekun ise rere fun enia Anobi kan lo so bayi pe, bi enyin ba ni igbagbo ti o kere bi horo Mustadi, enyin le pase fun oke wipe ki o sidi lo sinu awon okun. Nitorina ejeki gbo gbo wa ni gbagbo, ki a si jeki o po si. Ki Olorun ran wa lowo.

ORO MUSULUMI

Ilu Tatambulu ni wahala die lenu ojo meta yi ni to ripe awon omo ake ko mba ijoba fa ijegbon. Lona keji ijoba ti ti lekun gbogbo ile eko, yio si wa be titi owon o fi mu ofin awon ologun ku ro (Martial Law) Awon Imale ilu pakis tan ti se paramu lati ma gba ebun saka, ni gbati nwon ba gba a tan nwon o tun pin fun awon ti a gbi lowo re, ey ti aba pin ti o seku ao ko fun ijoba lati lo bi o ti to.

O tun di ose to nbo lagbara Olorun. E ma ka iwe Irohin Imole ni osose fun kika nipa Islam ni ede yoruba anfani lo je fun eyin ti ko le ka ni ede Gesi.

## "OBINRIN PELU OGBON AREKE-REKE"

O BERE LATI OJU EWE KETA

Obinrin yi dahun, o ni "kabiyeyi, ki ade pe lori, ki bata pe lese, o si tun dahun bayi pe:- !!Nje o ranti ojo ti ewure nre aro, ti Ifa sikun efun (powder)!! (Nigbati oba gbo, enu yaa, eru si ba gidigidi, o si tun ranti pe obinrin yi lo je ki oe joba, nitoripe on lo ji ewure gbe, lo si tun gba on lowo awon ti o wa yo ile wo.

Bayi ni oba pase pe ki nwon tu obinrin yi sile ki nwon we fun, ki o si tun gun ori oye re pada ati pe nwon ko gbodo fi owo (knife) obe kan rara.

Okan ninu awon ayaba yi ti o ri nwon nigbati oran yi sele tun se irufe asemase bayi, sugbon oba la idi re ti o fi da Obinrin akoko sile fun un, o si pase pe ki nwon pa Obinrin alaimokan na.

ITAN NA PARI O.

Olotu mo dupe aye ti e gbe mi o. E ko ni sise o,